U. T. C.
DEPARTMENT STORE
SERVES
YOU
WELL

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

**Akiyesi Pataki**

A fiwe y i ș e ikede s i awon Așoju iwe irohinEleti Ofe kakiri agbaiye wipe, enikẹn ti ko ba fi owo ti o ti je ranșe si wa, o pe lejo, ako si ni fi iwe irohin ranșẹ si enibẹ mọ.

VOL. XI No. 622. LAGOS, SATURDAY, MAY 2 — MAY 8, 1959. KOBỌ MEJI (2d)

# Arun Yinrun-Yinrun Ati Ilegbona Be Sile Ni Oke-Oya

SOKOTO. Irohin de si etigbọ wa wipe arun yinrun-yinrun ati arun Ilegbona, ti bẹ silẹ nisisiyi nilẹ Oke-Oya, ogunlọgọ awọn enia ni ẹmi wọn si ti rasu nitori arun nwọnyi.

Bi arun yinrun-yinrun ti nṣe jamba kakiri ilẹ Șoko-to, Bauchi Kano ati ni ilẹ Meiduguri, bakanna ni arun ilẹgbona npa awọn enia la-gbegbe ilẹ Zaria, Kaduna, Jos ati ni Ilọrin.

Ni lọwọlọwọ yi enia mejidilogun ni a gbọ pe arun yirunyirun pa danu ọgọrọ enia ni a si ti gbọ wipe nwọn yọ lọ fun ti arun ilẹgbona.

Asiko to nisisiyi ti ijọba Ariwa, tabi ijọba ilẹ awọn Hausa l'Oke-Ọya ti nwọn nilati w a ọ n a ti arun Yinrun-yinrun yi a t i Ilẹ-gbona to wọpọ nilẹ won yio fi dinku gidigidi, t ko b a l e kasẹ n i l ẹ pa ...tapata.

Ki O...luwa sọ wa lọwọ ajakalẹ arun.

## Enito Se Moto To Yara Gb...yi Nile Gesi



...a nwo ninu aworan yi ni Ọgbeni Tony Vandervell Enii... awon moto kekeke ti nwon fi nsare ije nilu Oyinbo. eniti o șe ... ti o gbe ife fadaka ti Dewar fi șe italore fun ẹniti On ni a nwo ... ninu ere ije be. moto re yege ... n j e Vandervell y i s o wipe b i ajinde ara Ọkunrin t i ... moto ti yio yara ju eyi ti on ti șe lo ti elomi-ba je on le tun șe ...'yi ere ije Moto pada si ilu England. ran le tun fi bori gb...

## AYO ABARA ...TI... ...NTIN!



Alaiyeluwa Ọba Ọlọwọ ti ilu Owọ ni a gbọ wipe iyawo rẹ Aya'ba Alice Ọlabọde bi ọmọ mẹta nigbakanna, Ọkunrin meji ati Obinrin kan. Ki Ọlọrun ba ... wo awọn ọmọ na, n si ki n ... luwa ati ayaba na pẹ; Alaiye... E ku ewu.

## KI IȘE KOGBEDE, EBU ...bẹ-

Obinrin kan pe Ibo ni Kog-de nitori oro yi awon gbe ara won de kotu.

Adajo bere lowo obinrin na pe eșe ti o fi pe ni kogbede?

Obinrin - n i t o r i ti ko gbo ohun ti mo nso ni.

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches Througout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE. E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
E.Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

## Ayinike Ati Ayinipada

(Apa 1)
Lati Ọwọ Ẹsọ

**Nigbakan, lasiko ti oju wa ni orukun, ti nwọn nja ogun Nami-Nnale, awon ẹranle ati ẹranko o ma ba ara won ja Igba nigbati oṣupa ba yo.**

Latigba ti nwon ti nja ija koiti kan awon eranko bi Ajanaku, Gidigidi, Afirubojo Ẹfon Esuro, Egbin, Ijakumo Ẹkun Turuku ati awon agba ninu awon eranko. Nigbati ija ba bere lati ori ...-ile ati Ekute oko, titi ti ija ... dori Mumuni ile ati ... oko ibe ni ija ma ... fi mo, ti ... si ... si ile rẹ Mumuni ile ati Obuko. Mumuni oko ni Lagido.

Nigbati ija ba kan Obukọ, a ma darin bayi wipe:-

Giri-r-r-gbo gidigbo, He!
Obukọ lemọṣo, ija lemọṣo

Nigbati Ọbọ, Lagido ba si fẹ bọ si agbo ija a ma darin bayi pe:- Giri-r-r gbo gidigbo, he!

Ọbọ takiti nigboro niṣo
Gboro yẹ yẹ, gboro yẹ yẹ

Nigbati nwon ba bẹrẹ gidigbo bi Obukọ ba gbe ọbọ roke-rodo ti o ba wipe ki on la a mọlẹ Ọbọ yio pe ọfọ bayi pe. "Agbeti ni ti ọmori odo. E ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ. Lọsẹ ti o mbọ e o gbo bi ija na ti se yi kan Ologbo, ti o si da gbogbo ẹranko laiku ẹnikan.

## AYẸYẸ IṢE AKOSO IJỌBA ARIWA

Awon ọkọ ofurufu meji ti o jẹ ti ogun gidi, ni yio bẹ ilu Eko wo ni ọjọ Monday ti iṣe ojo kejidinlogun oṣu May, ti yio wa fi ere gbeiyefo dahin lori omi ọsa l'Ẹhingbeti, nigbati nwon ba wa ba ijọba ile Ariwa ṣe ayẹyẹ ajọyọ ojo ti nwon di aladaṣe ijoba ara won.

Awon ọko ofurufu na ni nwon npe ni Arro Vulcan ti o lagbara ti o si le fo soke bi iwon ẹgba mẹdọgbon ẹsẹ.

Irufẹ ere bayi ni ọkọ gbeiye... wa se ni asiko ti Alaiyeluwa Ọ... Obinrin wa bẹ ilẹ yi wo ninu ọdun 1956.

A gbo wipe bakanna ni awon ọkọ ofurufu na yio ṣere ... Katsina, Bauchi, Minna ati Ilọrin


## CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENTS :-

IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.


## Alakoso Ijoba Ariwa Be Ilu Eko Wo.



Irohin kan wa wipe Alhaji Ahmadu Bello ti iṣe asiwaju awon Oselu (Premier) nile Hausa dakan wa bẹ ilu Eko wo lati wa f'oju kan Alhaji Abu Bakare ẹniti iṣe Prime Minister fun ijoba apapọṣe.

A si tun gbo wipe awon ijoye ninu awon oṣelu meta ni o tele lehin wa si Eko. Ohun ti a gbo pe nwon fẹ soro rẹ ni oro kan ti o jẹ mo ile Hausa.

## ẸNI BA D...PẸ ORE ANA, YIO GBA OMIRAN.

Lati ọwọ Ẹsọ

Nigbati Olodumare fẹ fi Ori jẹ oga fun gbogbo awọn Irunmọlẹ, o mu obi ore, o fi lelẹ, o ni ki gbogbo awọn Imọlẹ wa pa obi na.

Apa de ibẹ o la a ti ẹsẹ de ibẹ, o la a ti, Ogun de ibẹ, o la a ti, Ọya, Ọsun, Ṣango, Elegbara, Orisa Oko, Ọrunmila, Olota, Olokun, Sọpọna, Bayanni, Kori Dada, Ibeji, Talabi, ati gbogbo awon Orisa lo de ibi obi yi, ti nwon la a ti.

Gbogbo won wa joko ti obi na lorun, nwon nreto ẹni

(Wo yoku loju ewe kejọ)

# Owe Ile Yoruba

Bi a ba korira amori a o si se Shango.

2) Ti a ba ran omo ni Iyun ni Ajase ti a ko ba ri Iyun a ri owo eni.

3) A so okun mo aparo lese o degbe adie ninu Ile.

4) Bi a ba tori igi gbo'di a si suna fun ni ya.

5) Ki a to pa awoko ki ajeki omo re kio to oro so

6) Aguntan ko pe ohun ko se omo Ewure Ewure lo n i o n ko se omo Aguntan.

7) Ninu ikoko dudu n i Eko funfun ti jade wa.

8) Omi Amola ki itoju alejo ho, eje a lo le.

9) Oran ti oloko ba fi se ekun sun, ti aparo yio fi se erin rin.

10) Elulu ni oran ti on ko ba fi ni dun obe gbogbo ti apa ti itan on ni yio ya run si i.

11) Akoko mode Iresa, ole ri ale'nu oya ju ori ale ode lo.

12) Akoko daripon inu mbi odidere.

13) Ti a ko ba se bi elede lona Ijebu a ko le se bi Adegboro loja oba.

## Omode Obinrin Sonu

BENIN. Ọmode obinrin kan bi omo ọdun mẹtadinlogun omo ilewe ilu Ibini ni omo na ti di awati lati ojo 22nd April, 1959

Ọmo ilẹ Ibo ni omo na, o mo'ra diẹ o si ga to ẹsẹ merin ati ẹsun meta.

## Bi Olorun Ko Pani Oba Ko Le Pani

Lati ọwọ JOSEPH SUNDAY BOLARINWA

Ni igba kan awọn ọkunrin meji wa ni ilu kan, ekini a ma jẹ B'Ọlọrun ko pani Ọba ko le pani, ekeji a ma jẹ B'ọba ko pani. Ọba kan gbọ oruko awon ọkunrin wọnyi, o si ranṣẹ pe wọn. Nigbati awọn de ọdọ rẹ, o bere orukọ wọn. Ekini ni on a ma jẹ B'Ọlọrun ko pani ọba ko le pani, ekeji ni on a ma jẹ B'ọba ko pani Ọlọrun ko le pani.

Bẹni ọba mu aṣọ funfun o fi i fun B'Ọlọrun kopani o si fi aṣọ dudu fun B'ọba kopani o si ran wọn jade, ṣugbọn ki o to ran wọn jade, o ti ran tafatafa kan lati lọ sapamọ de wọn ninu igbẹ, wipe, bi awọn ọkunrin meji yi ba mbọ ki o tafa ba alaṣọ funfun ki o si pa a.

Nigbati awọn ọkunrin wọnyi jade kuro niwaju ọba, B'ọba ko pani bẹrẹ si sọ wipe, aṣọ funfun ni on fẹ, ṣugbọn B'Ọlọrun pe, ki o jẹki awọn ṣe paṣiparọ, eyini fi funfun tirẹ fun B'ọba kopani, o si gba dudu tirẹ.

Bi awọn si ti rin siwaju diẹ ni awọn ri tafa ba B'ọba kopani, loju kanna o si ku. Bẹni B'Ọlọrun ko pani sare pada tọ ọba lọ, o sọ gbogbo ohun ti awọn ṣe fun ọba ati bi awọn si ti pa ekeji on.

Ọba na si dahun wipe otitọ ni orukọ rẹ bi Ọlorun ko ba pa ni, ko si eniti o le pa ni. Ọba si da ile rẹ meji, o da ona rẹ si meji, o fi i fun okunrin na.

E o ri iṣe Ọlorun bi o ti lobi to, iṣe Ọlorun a ma ma ri di ni.


# NISISIYI!

FUN IGBA AKOKO NILE NIGERIA...

AWỌN ONIṢOWO

**THE NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.**

YIO MA ṢE

ETO OHUN IDANA GAS SINU ILE LATI MAFI DANA

**Ale fi Gas pẹlu Meter rẹ sinu ile ti a ngbe Koni agbekiri. Ko si ni ṣalai muna wa nigba kan. Ko lewu, o rọrun, lilo rẹ din inawo ku.**

ẸNYIN KỌLE KỌLE, ONILE ATI ẸNIKẸNI TI O BA FẸ LILO RẸ KI

O KỌWE FUN ALAYE KIKUN LỌDỌ :-

**NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.**

2, ITAPEJU AVENUE, P.M. BAG 1040 APAPA TELEPHONE 55295.

Iye owo rẹ ati gbogbo alaye nipa rẹ ni ao se fun yin lọfẹ.



**E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE**

LỌSỌSẸ OKUN FUN IROHIN ALADUN

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL XL NO. 622. SATURDAY MAY 2 - MAY 8, 1959.


## Ase Onikunmo Leyi!

(NIGERIAN COLLEGE OF ARTS, SCIENCE & TECHNOLOGY)

Ọrọ ile ẹkọ giga ti ilu Zaria ti olori awọn olukọ ile ẹkọ na ti, se enia l'ẹnu pupọ. Lọna kini, gbogbo awọn ọmọ akẹkọ to mbẹ ninu ile ẹkọ na fẹrẹ jẹ eyiti ijọba ati awọn onisowo ṣe onigbọwọ wọn lọ si ile ẹkọ na, fun ẹkọ ati imọ to piye lati le fi gbe ogo ilu wa, ani ti ilẹ Nigeria ga lẹhin ọla.

Lọna keji ewẹ, ki ba ti ṣe irufẹ ile ẹkọ ti yio fun wa ni awọn ọjọgbọn ninu ẹgbọn ori, iṣẹ ọwọ ati iṣẹ-ọna lorisirisi ti yio wulo fun orilẹ-ede wa, paapa ni asiko die ti a nf'oju sọna rẹ yi, ani nigbati a ba di ominira ara wa ti ao nilati ma da nkan ara wa ṣe yika gbogbo ilu wa tabi ilẹ Nigeria ni iru ọrọ bayi yio wa ṣẹlẹ.

Lotitọ ni a fi gbọ 'pe awọn ti yan awọn Igbimọ ti yio wa idi okan ti o fa sababi rukerudo to ṣẹlẹ nile ẹkọ na ki ase onikumọ nipa titi ile ẹkọ na to wọ? ṣugbọn awọn ti ti ile ẹkọ na nisisiyi ti ju ọsẹ meji lọ, ọrọ ẹkọ ki i si ṣe ọrọ ti a le fi ọwọ yẹpẹrẹ mu, nitorina, a fi wosika wa yi kesi ọlọla Alakoso ile ẹkọ Ọgbeni Aja Nwachuku ati Alaga ile ẹkọ ti ilu Zaria na Mallam Shettima Kashim wipe ki awọn tete ba wa mojuto ọrọ ti ile ẹko na. Ina ni oro ile eko na jẹ fun gbogbo ilẹ Nigeria, ti ako gbodo fi s'ori orule sun.

A duro bayi.

## Irin Ajo Lo Si Meka Ati Medina

(Lati Ọwọ Alhaji)

Lẹhin ti a ba de ilu Madina, ao lọ si Mọsalaṣi Madina ao ki irun ao wa,se ṣiara ni iboji Anọbi Muhammadu, ati iboji Abu Bakar ati iboji Humoru lẹhina ao si fakia ao wa ṣe Ṣiara Fatimọ, ati awọn bẹbẹ iyẹn to meje lẹhina ao lọ si Oke Hudu, ibiti Anọbi gbe jagun ao ṣiara awọn ọmọ ẹhin Anọbi ti wọn ku sibẹ awọn mẹtale-lọgọrin loku ti wọn si sin sibẹ.

Lẹhina ao lọ si mọṣalaṣi marun ti awọn ọmọ ẹhin Anọbi kọ, mọsalasi na ko jin si ara wọn rara ao yan Nafila meji ninu mọṣalaṣi kọkan ao tọrọ nkan ti a ba fẹ, lẹhina ao lọ si mọsalaṣi Kuba mosalasi ti Anọbi Mohamad kọ fun ara Rẹ, ti o si nki irun, ki o to wa kọ mọṣalasi ti igboro mọsalaṣi igboro yẹn ni won sin Anọbi Mohammad papa si. Lẹhina ao lọ yọju wo Kanga ibi ti oruka Anọbi bọ si, ko jina rara si arawọn o fẹ rẹ jẹ wipe wọn fi ẹgbẹ kan ẹgbẹ ni. Lẹhina ao pada wa pada wa si igboro Madina, ao ma lọ ki wakati ni Harami.

Mosalasi Madina dara pupọ iye opo ti o wa ni mọsalasi na jẹ 528 (528 Pole) iye ina ti o wa ni ara opo kankan jẹ mẹrin-mẹrin iyen ni wipe ina to wa ni gbogbo opo mosalasi na jẹ 2112, gbogbo idi opo na idẹ ni won ṣe. Idi opo kọkan ribiti rẹ jẹ ẹsẹ mẹwa (10 ft) Ina Iletiriki ala tegun (Electric fans) to wa ni mosalasi yi jẹ 528, nitorina kosi oru nibẹ rara (Doors) ti o wo mosalasi yi jẹ mẹrindinlogun (16 Doors) Ọlorun fẹran Anobi pupo. Bi enia ba de mosalasi ni alẹ yio dabi enipe osan ni oluware wa. Gẹgẹbi oro Anobi Muhammad enia ni lati ṣe Jimo kan ni Modina tabi ju bẹ lo. ki oluwarẹ to kuro nibẹ.

Ti a ba kuro ni Madina, ao tun pada wa si Jidda, ẹlominran le wo moto tabi oko ofurufu. Bi enia ba wo moto, oluwarẹ yio lo wakati mejila tabi jubẹ lo ki o to de Jidda nitori o to buso irinwo (400 miles) ṣugbon bi enia ba wo oko ofurufu wakati kan ati ogun iṣẹju ni iyẹn jẹ (345 miles) ti a ba pada de Jidda awon oloko ofurufu yio ko eru yin sinu moto kan loto awon ero papa yio wọ Bọsi Bus awon yio ko yin lo si Madinatu Hujaji. Ile yi je ile ti awon ero nde si ina ati omi wa ni ile yi. Ẹo gbe ibẹ titi igbati o ba wun yin lati lo si Mecca bi ẹ ba fẹ lo si Mecca Ẹo san owo Bosi Bus £1.2s. 6d tabi kiẹ haya moto ayokẹlẹ bi ẹ ba to mẹfa tabi ju bẹ lo ninu moto ayokale kan. Ẹnikankan yio san 12/6d de mecca Jidda si mecco jẹ buso metalelogoji (43 miles)

(koiti pari.)






No 73

## FEDERAL ELECTIONS 1959

### REGISTER OF SYMBOLS

Regulation 141 of the Elections (House of Representatives) Regulations 1958, requires the Electoral Commission to keep a register of symbols for use at elections and empowers a political party to apply to the Commission for the entry in the register of a symbol to be used by that party at the elections. The Regulation goes on to provide that the Commission may register the symbol on payment of a registration fee of £20 to the Federal Treasury provided that it is satisfied that no other symbol of the same design is registered, that the symbol is distinctive from any other symbol which is registered and that its use will not be contrary to law or morality.

2. The Regulation prohibits the registration of certain symbols including any device or emblem which is associated with the regalia of a chief, or with any religion, cult or tribe.

3. In order that the Commission can have sufficient time to consider applications and to make arrangements for the preparation of symbols for use on ballot boxes, they have decided that all applications for registration of symbols must be submitted to the Secretary, House of Representatives, Lagos, NOT LATER THAN SATURDAY THE 30TH OF MAY, 1959. An application for registration must be made by the Secretary of the party Concerned.

J. J. WARREN
SECRETARY
ELECTORAL COMMISSION

## Arun Buruku Kan Wo Ile Ghana.

ACCRA. A gbọ irohin wipe iru arun kan ti a ko gburo rẹ ri, ṣẹṣẹ wọ ile awon Aganyin, o si ti bere si pa awọn ọmọ oponlo bi danga, oro arun yi mu awon Dokita ati Oyinbo lomi ,nitoripe iru iṣowọ pania arun na se ajeji loju won.

Nilu kan nile Aganyin ti a npe ni Abodom ni arun na gbe sẹlẹ, o si pa to ọmọ mọkanleladọrin nibe. Oniṣegun ilera ilẹ Ghana koiti le so iru etutu ti a le se fun arun ti o npa awon ọmọde bẹ.

Ninu oṣu January ibẹrẹ ọdun ni, ọmo mẹrindilogbon lo ku. Ninu oṣu February ti o tele, omo mejidilogun lo ku, ninu oṣu March omo medogun lo ku, ati ninu oṣu ti a wa yi odi ọmo mejila ti o ṣalaisi.

Awon Dokita ṣi nwadi etutu ti o yẹ fun arun na.






## "Ajapa Ati Awon Elegbe Re."

(Lati owo Y. Ade Buraimoh)

Awon Iyawo Ajapa ti to Ọbẹ si inu awo tan, kia kia lo si bere si gbe siwaju awon Elegbe ẹkẹ won, ki a ma fagun lọ titi won jeun tan, Ajapa gbe oti sekẹtẹ kale fun won, ri ri ti wọn ri bayi, inu won dun, gbogbo won si pariwo pe afi iwọ na ! afi iwọ na !! afi iwọ na !!! jagunlabi. won ko mọ pe eiyẹ agbigbo ni o se fun awon je rara, ni igbati won wa ninu oti yi lọ, oju won fẹrẹ masun, nigbana ni Ajapa wa sọ pe, on mu ileri on sẹ loni, eiyẹ agbigbo tie ni ẹko ni je lailai aiye yio fi parẹ ri ẹ je loni yi o.

Gbigbọ ti won gbọ eyi, inu gbogbo won bajẹ, eni ti o nkọwọ bo ona ọfun "Ọrun" nkibọ lati bi onjẹ ti won je na, sugbon ẹpa ko boro mọ.

Won wa ro nkan ti won yio se fun Ajapa titi won ko ri, ni won ba bere si na, to bẹ ge, ti ẹhin rẹ fi le titi di oni yi.

Itan yi ko wa pe, kia madalẹ elegbe wa, kia ma dalẹ enia ẹni ti o ba dalẹ, ilẹ yio da, ẹhin re ko si ni dara rara.

Akiyesi:- Ẹnyin okawe Eleti-Ọfe e ma ra ni ọsọsẹ okun fun itan aladun. Ajinde yin yio ma je o aṣẹ.

## Alafin Gba Alejo Pataki



OYỌ—Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni oba Alaiyeluwa Bello Gbadegesin, Baba lafin Oyọ, on ni eniti o ran awon ijoye rẹ lori esin lọ pade Oloye Awolọwọ pelu ilu ati ifọn ati awọn ọde ti ibọn nkun bi ojo.

Gbogbo awọn enia l'ọkunrin l'obinrin ti o gbo wipe Oloye Awolowo mbọwa, lo fi ese ba wọn rin irin buso meji ki nwọn to kan Oloye na, ti gbogbo enia nkigbe wipe Awo ! Awo ! ! Ile Ọyọ ndun yungba, awọn enia dabi emi, eniti ko le rin ni ki won gbe on, lati lọ pade Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, akonije ẹgbe Afenifẹre (Action Group)

### IFẸNUKONU NINU TUBU

Ọkunrin kan Major Jesus Sosa Blanko ara ile Kuba, ti ọwo olopa te ninu awon Ọlosa ti nwon lo fole kan ko eru, awon mejidiladota ni olopa mu ti nwon si fi nwon sun ẹsun apania, adajọ ni kia lo yegi fun won.

Nigbati akoko iku won sunmo etile, ni okunrin na Major Jesus Sosa Blanko eniti o ti fi igba kan je ogagun ri sọ wipe on fẹ gbe ejọ na lọ si Kotu kotẹmilorun, ṣugbon bi on yio ba tile ku na ki nwọn ba on pe iyawo on wa ki o wa fi ẹnu ko on lenu ki on toku.


Kere o !

**Ati ni orisirisi ogun German to ṣeṣe de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ ki o to tan.**

J. A. AJAO BROTHERS

**MEDICINE STORES**

**7 Egerton Road Lagos**

## Bi Ako Ba Pa Iji Han Iji Eru Ko Mba Iji

Nigbakan, nigbati Ọrunmila mbẹ nile aiye o si awọn ọmọ Awo mẹta ti nwọn ti gbo sun Awo. Ifa nwọn a si ma jẹra, nigbati Ọrunmila ko ba si nile, awọn nyan ẹbọ nwọn si nṣe etutu. Nipa igbalaye ti Ọrunmila gba awọn ọmọ awo rẹ mẹtẹta nwọnyi laye, o jẹki nwọn ri ọga wọn fin. Nigba mirin Ọrunmila a ma bẹ nile awọn a si ma jẹra, gẹgẹbi o ti gba wọn laye si.

Ọrunmila feran awọn ọmọ awo rẹ mẹtẹta nwọnyi, to bẹ ti awọn mẹtẹta fi nlọ soju Ọrunmila ni awujọ awọn Irunmọlẹ. Awọn mẹtẹta nwọnyi ti Ọrunmila fẹ patapata tobẹ ti nwọn fi sọ loju Ọrunmila paapa wipe kini yio se fun wọn.

Bi a ko ba pa iji han iji,
Eru ko ni ba iji,
A difa fun Ọrunmila
Ki o se mẹlọ-mẹlọ nipa
awọn ọmọ Awo rẹ.

Lọjọ kan, ti Ọrunmila fẹ ko gbogbo iya arifin ti awọn ọmọ awo rẹ ese si, o pe awọn ọmọ awo mẹtẹta jọ, o wi fun wọn pe nisisiyi, mo nlọ si ajo, nitorina, titi ngo fi pada de, ẹnikan ninu nyin ko gbọdọ se ọpọn poro Ighin mi.

Ọrunmila atra, o si lọ si ajo. Kini o jade nile si nṣe ni gbogbo awọn enia nro wa lati yẹ ifa wo, awọn ọmọ na koko fẹ mu ase oga wọn se sugbọn nigbati awọn enia ko dekun lati ma rọwa lati yẹ ifa wo, oju wọn yan si ọwọ ti awọn nko wa.

Awọn ọmọ awo mẹtẹta Akaheregbe difa, Adubule-difa ati Arogun-tokowale bara won so pe, kini Ọrunmila ro ki o to sọ wipe awọn ko gbọdọ se ọpọn poro, bi nwọn ba se nkọ, kini yio se fun wọn kelen nse fun wọn ni?

Akaheregbe-difa yọ iporun re bi o ti da a... Ọrunmila yosi o bere pe ifa kini eyiti o da ni' ọmọ Awo si dakun pe Irete-Okanran, loju kanna ẹr n ọmọ Awo na yin si ẹhin, o si ku bakanna ni Adubule-difa se se, oun na si ku. Bi Arogun-tokowale ti da ifa tirẹ, ... Ọrunmila yọ si ... bere wipe ifa kinni eyiti o da ni, ọmọ Awo na yara gbe ọpọn ifa soke o wipe nkọ nko-o-o, oluwa mi iku deuc agbo. Ọmọ awo na ye. Iru nkan bayi lo ma nsele nigbati Babalawo kan ba gbe ọpọn ifa soke wipe ajowo o, ohun ti a ba jọ won lo gun rege.

## Itan Elegbeje Ado

(Lati Ọwọ Y. Ade Buraimoh)

### ARABINRIN NA DI ILE

Bi Obinrin yi ti b ọ r a s i l e tan ile Ọba lo mu ori le, o si ko, oro fun Ọba, gbara ti Ọba ti gbo ọro rẹ tan, Ọba ranṣẹ pe alagogo rẹ, o si ni ki gbogbo Ọkunrin ati Obinrin ilu ki won pese si Afin on ni agogo mẹrin abọ irole oni, lori Elegbeje-ado yio wo lu ni ọla. Kia masa alagogo rẹ ti ki agogo mọlẹ, o si nlu kalkiri ilu. Gbigbọ ti awon ara ilu ngbo, won nfi eti kan ara won, gbogbo won si pese si Afin Ọba ni agogo merin gere won nreti oro ti Ọba yio sọ fun won, ti aja ti eran loduro si Afin Ọba.

Ọba de ita, owo gbogbo ori awon enia lọ, gbogbo won si di mo ara won bi sadin ni elege Ọba bere ọrọ. o ni kere o kere o kere! Ki elenu panu rẹ mọ, ki olomọ fi oyan (ọmu) si ọmọ rẹ lenu. Gbogbo won sebẹ gẹgẹ bi Ọba ti wi, gbogbo won fi eti silẹ lati gbọ ede ti Ọba yio fọ jade lenu.

Ọba ni ki gbogbo yin mura lati lọ pade jagun wa ni ọla, o ti rin ajo de, edun Kẹdọgbon to si ti lo nyi, nigbati o ba wa segun awon ẹlọsa tan, lo ti gbe ogun ti Ebọra Ọsundun ti inu igbo ọsundundun. O si ṣegun rẹ, pataki julọ, O mu Ebora na wa laye fun gbogbo wa lati fi oju ri dada. Gbogbo won si gba pe Ogo Oluwa to fi pada bọ wa si ilu re, awa na yio fa ọmọ yọ, ao si ṣe ẹyẹ fun gẹgẹ bi o ti tọ ati bi o ti yẹ.

### "ILẸ ỌJỌ KEJI MỌ"

Ọba pe awon ẹmẹwa re, o ni ki won lọ se ẹṣọ fun ẹṣin (Horse) ti on yio gun lọ pade Ọdẹ Elegbeje-ado Awon ẹmẹwa rẹ si se ẹṣọ iyebiye fun ẹṣin Ọba na, gbogbo ara ilu mura tan lati lọ duro si enu odi ilu, ilu si nro gudu-gudu Ọba papa ti gun ẹṣin re, ti o si wọ ẹwu iyebiye pẹlu, bi Obinrin, Ọkunrin ti ni aṣọ to bi won se mura ni ọjọ na ti won si duro si ẹnu odi ilu ni agogo mewa abọ owuro, kosi eni to lọ si oko rara, kosi si eni to lọ si odo pẹlu.

### "ỌDẸ ELEGBEJE ADO YỌ LOKANKAN"

Yiyọ ti ọdẹ Elegbeje-ado yo ,ti ọmọ rẹ ri lokankan, o wa da orin kan bayi ori mi dori re, ori mi dori, re ori mi dori re, eba mi yo ori mi dori re. Gbigbo ti awon ara ilu gbo eyi, gbogbo won bere si gbe orin na Ile obo Ebosa le nko orin na papa. Gbigbo ti Elegbeje-ado papa gbo orin yi, ori re ya, on papa na wa da orin kan bayi pe mo dupe, mo dupe, iku ti o pa Erin nbe lese igbo, iku ti o pa Efon owa lalo, iku ti yio pa mi o wa ninu apo, Edumare so temi dire. Gbogbo won na tun

(Wo iyoku loju ewe Keje)

# Ojojo Lo Ns'ogun



Ara ogun ko le, ni oro ti a le so lori amodi die ti o nṣe omoba obinrin olola Princess Margaret ti o ba aya'ba ti iṣe iya to bi Alaiyeluwa oba Gẹsi fo lo silu Pari fun ibẹwo ojo marun pere.

Gbogbo awon enia ti o ri omoba na ninu ile isin ti St George's lowuro ojo osẹ lo so wipe oju rẹ rẹwesi, arẹ ara si farahan lara rẹ, o mbẹ ninu ile Aṣoju Gẹsi nilu Faranse ti o nsinmi.

Plushes, Velvet, Velveteen, Damask & Building Materials.

PLEASE CONSULT

Okunowo Brothers

63, Massey Street. (Faji Market)
LAGOS, NIGERIA.

The House where Curtesy & Satisfaction are Guaranteed

# Omode Obinrin Sonu.

BENIN Ọmode obinrin kan bi omo odun mẹtadinlogun omo ilewe ilu Ibini ni omo no ti di awati lati ojo 22nd April, 1959.

Ọmo ilẹ Ibo ni omo na, o mọ'ra die osi ga to ẹsẹ mẹrin ati ẹsan mẹta.




## Keke Da Rocha Yio Di Seranwo Ni Iddo

EKO. Kẹkẹ alafọwọfa (Rickshaw) ti Ologbe Candido Da Rocha ma nlo ngba aiye rẹ fi jẹ faaji lọ ode iru eyiti nwọn nlo nile Japan ati Chana, ninu odun 1870, ti awọn Aṣoju ba nian ile rẹ, nwọn si gbe kẹkẹ na lọ si ọdọ P.W.D lati tun kẹkẹ na ṣe ki nwọn si fi patẹ si arin ode gbangba ni Iddo fun anfani awọn ọmọ Eko ti ko mọ iru Kẹkẹ alafọwọfa be ti a ti nlo siwaju ki moto to de.

Awọn ẹnia ti o nfa kẹkẹ awọnyi ni akoko na ni awọn ti a npe ni Ilabiru, Awọn ara Eko si nfi oriki bayi ki wọn pe Ilabiru baba ọbọ bantẹ niwaju, iru lẹhin.

Ṣugbọn lode ti oni, ko si ọbọ ni Idere mọ, ọkan na ti o ku ewu ẹtu l'o nwọn, ojọ. Gbogbo awọn Ilabiru ojọ kinni ti di Manager, Sẹkitẹri, Trader ati Akọwe. Ohun ti ara Eko njẹ ni awọn na njẹ. Lailai ni awọn ti nsọ pe olowo lo njẹ gbure, ti talaka si njẹ efọ ẹsun. Ati olowo ati talaka lo njẹ gbure nisisiyi.

## ITAN ELEGBEJE ADO

(O bẹrẹ loju ewe kẹfa)

gbe ariu yi yun, pe Edumare sọ temi dire ọba papa alara tun gbe orin na lesẹ

Kia masa ọba sọkalẹ lori ẹṣin to gun o si ni ki ọdẹ Elegbejeado gun ori rẹ on papa tẹlẹ ri ọkanṣoṣo ajanaku ti imi igbo kijikiji ni iṣe, o gun ori ẹṣin na, gbogbo ara ilu si nkọ orin ti o da fun wọn tele.

Ọpọlọpọ enia lo ba ọdẹ Elegbejeado de Afin ẹ... ti nwọn jo ti wọn lu ilu orisirisi ni ọjọ na Ọba wa se onjẹ lopọlọpọ ati mimu pẹlu ọjọ na, Elegbejeado ko le sọ nkankan ninu ohun to fi oju ri ninu igbo, toripe ayọ ọjọ na ga pupọ kọse fi ẹnu wi, to fi jẹ pe ki wọn to kuro ni Afin Ọba oto agogo mejila oru Ọba wa fi gbogbo re si Ọla lati gbọ irohin lati ẹnu ọdẹ Elegbejeado yi.

(Koiti pari)

## Oko Ofurufu Helicopter fi Agbara Re Han



Iru ọkọ ofurufu ti a nwo yi ni a npe ni Helicopter, gbogbo ara re jẹ kiki irun, nwon nfi agbara ọkọ ofurufu na han, gegebi yio ti wulo si, nigbati lilo rẹ ba ya.

Eyiti a nwo nisalẹ rẹ ti o dabi ọkọ igi ni irin idabu kereni, iru eyiti awon ọmo ogun Gesi lo ni asiko ogun.

Irin na wuwo to 6,736 lbs. o si fẹ to ogun ẹsẹ gigun rẹ jẹ ẹsẹ marundinogoji. Si iyalenu gbogbo enia, fẹrẹ ni ọkọ ofurufu na gbe irin kereni na gegebi o ti wuwo to. Ni ọdun 1958 ni nwon kọkọ gbe ọkọ ofurufu na jade nibi afihan ti nwon ṣe.

## Eni Ba DuPe Ore Ana, Yio Gba Omiran.

(O bẹrẹ loju ewe keje)

ẹniti yio wala obi na. O si se nigbati ori yio jade nile, 'ni Ejiogbe wa nki ifa yi fun pe:-

Eni ba dupẹ ore ana, yio gba omiran, a difa fun ori, o nlọ si awujo awon irunmolẹ lati lo pa obi ore. Nwan ni iwo ori awujo awon irunmole ti o nlo yi nko? Elepe wa nibe, Ologun wa nibe, Alawo wa nibe. ati bẹ, bẹ' lo.

Ori ji, o kori si awujo awon irunmole. Nigbati Ori yọ lokere ariwo ta ge wipe kinla! ori ni yio wa la obi on bi ?

Nigbati ori de ibẹ o mu obi. o gbe ehin le o si la-a wo-o ariwo ta ge-e. Gbogbo won diro mo odi kitikiti ni ori ba bẹrẹ si da won ni ọkankan. Oda Ọya sile Ira, o da Erinmi sode Ọwọ o da Ṣango si Ọyo, o da Ogun sile Ire, o da Olokun si Eko o da Ọṣun si Oshogbo, o da Ẹlẹgbara si Ketu, o da Ọrunmila sile Ifẹ.

Lati ojo na wa ni ori ti je oga fun gbogbo Irumole. Mole ti ko ba fi ti Ori ṣe, ara iku lo nya ohun ohun gbogbo ti enia ba nṣe laiye yi, bi ko ba si iranlowo ti ori egbe ni nkan na yio je.

Ọtototo, Ọrororo., Ọtoto li a nje epa, ototo la nje imumu, Tori-tori la fi fun oba Makin, ki o ba le fi ohun tori-tori fun ni. Ejiogbe.

## Owe Ile Yoruba

1 Ẹmi abata ni nmu odo ṣan, ọla baba ọmọ lo nmu ọmọ yan.
2 Bilẹ ba ngbe oşika, ti ko gbe olotitọ, bi o ba pẹ titi ore a ma sunı ni şişe.
3 Otitọ a pẹ, pẹ, bẹni oşika a pẹ pẹlu, şugbọn ilẹ lo mọ ẹniti yio tẹ on pẹ.
4 O wu aguala pe ki o mọlẹ to oşupa, şugbọn Ọlọrun ko fi fun.
5 Ojo owuro lo mbi olowo ninu, olowo gẹlẹtẹ iwofa gẹlẹtẹ.
6 Ibiti o ba wu efufu-lẹlẹ lo ndari igbẹ si ibiti o ba wu olowo ẹni lo nran ni lo.
7 Aşa mba ẹiyẹle şere, ẹiyẹle nyọ, ẹiyẹle nfiku şere
8 Gbi ni işu, ni gbi ni akasu igbẹnu agaran ni ekute ile on kanna ni igba akaşu bamba loke aga.

Baba ni igba di ogoje, ome ni ero ko wa si oja, pẹlupẹlu awon ẹru oba ko jẹki a patẹ.


## ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajẹla ọmọde agbọmola bi orişa, akọọlukọ ogun ti ndamọ l'ẹkun igbona, atata ogun ti npa o tutu rẹ warawara a jẹ bi idan, a gba bi ẹtu ibọn. O s'abiku di ikugbagbe, o ş'ọmọ ti nhehin l'ore, Ikọ ri i sa, Iba ko l'ọna tagiri, aiperi ri d'ẹkun iyọnu Olugbala l'ọmọ ti nyagbe yiin o kapa inu wọ, o iu jẹdi l'alupa gbogbo abiyamọ nyọ şẹşẹ, Ela ri i o roju, Ọrẹrẹ ri i o na'gbẹ bo'ra Eyi npa lemọ lodilẹsọ, ọrẹ ikoko, koşemani awọn abiyamọ, eni araiye njijadu ra. O de ilu Ibo, o dọga o de ilẹ Hausa, o d'ọba gbogbo Onişegun l'o sọ pe ko legbẹ gbogbo ọmọde lo nfẹ ẹ fun ilera

IGO KEKERE 2/6d IGO NLA 4s owo ọkọ loto.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES

18, Denton Bridge Street
P. O. Box 2 Ebute -Metta








Printed & Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, Lagos P. O. Box 467 phone 23370